# KRISTI BỌ́ ẸGBẸẸDỌGBỌN ENIYAN; O SI RÌN LORI OKUN

## Matteu 14:13-36

### ẸKỌ 93 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Nitorina ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ labẹ ọwọ́ agbara Ọlọrun, ki on ki o le gbé nyin ga li akokò. Ẹ mã kó gbogbo aniyan nyin le e; nitoriti on nṣe itọju nyin" (1 Peteru 5:6, 7).**

**I A Bọ́ Ẹgbẹẹdọgbọn Eniyan**

1. Ni ipadabọ irin-ajo iwaasu wọn, Jesu pe awọn Apọsteli si ibi aṣálẹ̀ kan lati lọ sinmi, Matteu 14:13; Marku 6:30-32; Luku 9:10
2. Ogunlọgọ eniyan tẹle wọn, wọn kò si jẹ ki wọn ri àye sinmi, Matteu 14:13; Marku 6:33
3. Aanu ṣe Jesu, O wo arun wọn sàn, O si sọrọ Ijọba Ọlọrun fun wọn, Matteu 14:14; Marku 6:34; Luku 9:11
4. Jesu yiiri Filippi wò, Johannu 6:5-7
5. Anderu ri ọmọdekunrin kan ti o ni ìṣù akara marun-un ati ẹja meji, Johannu 6:8, 9; Marku 6:38; Matteu 14:17
6. Awọn ọmọ-ẹyin n fẹ ki awọn ero maa lọ ṣugbọn Jesu wi pe, "Ẹ fun wọn li onjẹ." Matteu 14:15, 16; Marku 6:34-37; Luku 9:12
7. Jesu paṣẹ fun ijọ eniyan lati joko leto leto, Matteu 14:19; Marku 6:39, 40; Luku 9:14, 15; Johannu 6:10
8. Jesu fi ibukun sori akara ati ẹja naa, O si fi fun awọn ọmọ-ẹyin lati fun awọn ọpọ eniyan, Matteu 14:18, 19; Marku 6:41; Luku 9:16; Johannu 6:11
9. Ijọ eniyan jẹ, wọ́n yó, agbọn mejila si ṣẹ́kù, Matteu 14:20 Marku 6:42, 43; Luku 9:17; Johannu 12:13

**II Jesu Rìn lori Omi**

10. Awọn ọmọ-ẹyin wọ ọkọ̀ lọ bi Jesu ti rán awọn ọpọ eniyan naa lọ, Matteu 14:22; Marku 6:45
11. Jesu nikan lọ gbadura, Matteu 14:23; Marku 6:46, 47; Johannu 6:14, 15
12. Ẹru ba awọn ọmọ-ẹyin bi wọn ti ri Jesu ti O n rìn lori omi, Matteu 14:24-26; Marku 6:48-50; Johannu 6:18, 19
13. Jesu fi ọkàn wọn balẹ, O ni, "Emi ni; ẹ má bẹ̀ru," Matteu 14:27; Marku 6:50; Johannu 6:20, 21
14. Peteru rìn lori omi, Matteu 14:28-33
15. A mú awọn olokunrun lara dá, Matteu 14:34-36; Marku 6:53-56

## ALAYE

**Isinmi fun Alaarẹ**

Lẹyin ti awọn Apọsteli ti pari irin-ajo wọn, wọn pada wá, wọn si royin fun Jesu ohun ti wọn ti ṣe, Jesu ti mọ̀ pe o yẹ ki wọn sinmi, O wi pe, "Ẹ wá ẹnyin tikaranyin si ibi ijù li apakan, ki ẹ si simi diẹ" (Marku 6:31). Jesu a maa kaanu fun awọn alaarẹ. "Ẹ wá sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣíṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin" (Matteu 11:28). Iyipada nipa lilọ kuro laaarin ero a maa fi isinmi fun ara ati iṣan alaarẹ, ṣugbọn o di igba ti a ba wẹ ẹ̀ṣẹ nù kuro ninu ọkàn ki o to le ni isinmi. Ọpọlọpọ eniyan ni o n lọ si aginju, ori oke, tabi eti okun fun itura nigba ti o yẹ ki wọn wá sọdọ Jesu fun idande kuro labẹ ẹrù ẹ̀ṣẹ wọn.

**Aanu ati Iṣoore**

Bi Jesu tilẹ kuro laaarin awọn ero ki O ba le dá nikan wà, sibẹ kò binu, bẹẹ ni ko si kanra nigba ti wọn wá A ri, ṣugbọn aanu wọn ṣe E. Oun kò kaanu fun wọn nikan, O ṣe wọn loore – "O wo awọn olokunrun wọn sàn." Lẹyin naa nigba ti awọn ọmọ-ẹyin n fẹ rán wọn lọ lati ra ounjẹ, Jesu wi pe, "Ẹ fun wọn li onjẹ." Ikaanu kò jẹ́ nnkan kan bi a kò bá fi oore ṣiṣe kun un. Jakọbu wi pe, "Bi arakunrin tabi arabinrin kan ba wà ni ìhoho, ti o si ṣe aili onjẹ õjọ, ti ẹnikan ninu nyin si wi fun wọn pe, Ẹ mã lọ li alafia, ki ara nyin ki o maṣe tutu, ki ẹ si yó; ṣugbọn ẹ kò fi nkan wọnni ti ara nfẹ fun wọn; ère kili o jẹ?" (Jakọbu 2:15, 16).

"Nwọn kò ni ilọ" ni ọrọ Kristi nigba ti awọn ọmọ-ẹyin fẹ́ rán awọn ero lọ, Ọkan ebi ti o tọ Jesu wá kò ni lọ lofo, "Alabukún-fun li awọn ẹniti ebi npa ati ti oungbẹ ngbẹ sipa ododo: nitori nwọn ó yo" (Matteu 5:6). Jesu kò pese fun aini wọn nipa ti ara nikan ṣugbọn "o si sọ̀rọ ijọba Ọlọrun fun wọn" (Luku 9:11). Eyi ni ifẹ ọkàn Rẹ pe ki awọn eniyan le ronupiwada ki a si tún wọn bí si Ijọba Ọlọrun. Iwaasu Johannu Baptisti, ẹni ti a ṣẹṣẹ bẹ lori, ni pe, "Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀" (Matteu 3:2).

**Iṣẹ Iyanu**

Jesu ti O fẹ yiiri Filippi wo beere wi pe, "Nibo li a o ti rà akara, ki awọn wọnyi le jẹ?" (Johannu 6:5). O fẹrẹ dabi ohun ti kò ṣe e ṣe loju Filippi; ṣugbọn Jesu n fẹ ki ó mọ̀ pe "fun Ọlọrun ohun gbogbo ni ṣiṣe" (Matteu 19:26). Ọkan ninu ohun ti o ṣoro lonii ni fun awọn eniyan lati gbagbọ pe Ọlọrun n ṣe iṣẹ iyanu sibẹ. Awọn miiran wi pe ọjọ iṣẹ iyanu ti kọja; awọn miiran gbiyanju lati sẹ́ iṣẹ iyanu ti Ọlọrun ṣe ninu Bibeli. Ṣugbọn agbara iṣẹ iyanu ṣiṣe ni o jẹ ami iwaasu Ihinrere lati ibẹrẹ, awọn ami kan naa ni o si n tẹle iwaasu Ihinrere tootọ lonii. Bi kò ba ṣe agbara iṣẹ iyanu Ọlọrun a ko ba ti le fi iṣu akara marun-un ati ẹja meji bọ́ ẹgbẹẹdọgbọn eniyan. Bi ko ba ṣe pe a rán Ọrọ Ọlọrun ti i ṣe Ounjẹ Iye jade pẹlu agbara Ẹmi Mimọ́, ko le ṣe e ṣe lati tẹ́ ọkàn ti ebi n pa lọrun.

**Mu Un Wa fun Jesu**

Anderu wi pe, "Ọmọdekunrin kan mbẹ nihinyi ti o ni iṣu akara barle marun, ati ẹja kékèké meji: ṣugbọn kini wọnyi jẹ lãrin ọ̀pọ enia wọnyi bi eyi?"

Jesu dahun wi pe, "Ẹ mu wọn fun mi wá nihinyi." Olukuluku eniyan i bá jẹ́ le kọ́ ẹkọ yii – mu un tọ sọdọ Jesu! Bi agbara rẹ kò ba tó, ti ẹbun rẹ si kere, Jesu n pè ọ pé, "Mu wọn fun mi wa nihinyi." Ẹni ti o fi akara marun-un ati ẹja meji bọ́ ẹgbẹẹdọgbọn eniyan, "le ṣe lọpọlọpọ jù gbogbo eyiti a mbere, tabi ti a nrò lọ" (Efesu 3:20). Ounjẹ di pupọ tó fun gbogbo eniyan, agbọ̀n mejila ni o si ṣẹku silẹ lẹyin ti gbogbo wọn ti jẹ ti wọn si yó.

**Eto**

Nipa agbara Ọlọrun ni iṣẹ iyanu fi n ṣe ki i si ṣe nipa iwarapàpà. Jesu paṣẹ fun awọn ero ki wọn jokoo ni ẹgbẹẹgbẹ, araadọta ati ọgọrọọrun lori koriko tutu. Lẹyin naa, O gbé oju soke Ọrun o si fi ibukun sori awọn akara naa. Ẹ wo iru ibukun nla bi eyi! ẹ si wo iyatọ ti o wà bi awọn ọmọ-ẹyin ti n pín ounjẹ naa fun awọn ero! Bi a ba ti ri gbà lọdọ Oluwa to, bẹẹ ni a o le ṣe ipinfunni rẹ̀ to. Awọn miiran le maa ro pe ki ni ṣe ti a fi n gbadura si ounjẹ wa nigba gbogbo, ṣugbọn ki ni ṣe ti a ki yoo fi dupẹ oore pe Ẹni ti o le fi iṣu akara marun-un ati ẹja meji bọ́ ẹgbẹẹdọgbọn eniyan, Oun kan naa ni Jesu ti O n ṣe itọju wa?

**Awọn ti N Ṣe Iranṣẹ**

Awọn Apọsteli ni awọn ti a rán niṣẹ naa. Jesu wi pe, "Ọmọ-enia kò ti wá ki a ṣe iranṣẹ fun u, bikoṣe lati ṣe iranṣẹ funni" (Matteu 20:28). Bakan naa ni a pe awọn ọmọ Ọlọrun lonii lati ṣe iranṣẹ. A sọ fun ni pe, "Ẹ máṣe tọju ohun giga, ṣugbọn ẹ mã tẹle awọn onirẹlẹ" (Romu 12:16). "Nitori tali o pọ̀ju, ẹniti o joko ti onjẹ, tabi ẹniti o nṣe iranṣẹ?" eyi ni ibeere Jesu. Lẹyin naa ni O si tun wa sọ pe, "Emi mbẹ larin nyin bi ẹniti nṣe iranṣẹ" (Luku 22:27). Lati tẹle Oluwa ni pe ki a jẹ́ iranṣẹ ki a si ni ẹmi irẹlẹ.

**Akoko lati Gbadura**

Ọjọ naa ti Jesu rò lati sinmi pada di ọjọ iṣẹ ṣiṣe pẹrẹu, ti iwosan, iwaasu ati fifi ounjẹ bọ́ ogunlọgọ eniyan. Bi o tilẹ ṣe pe Jesu kò ni akoko lati sinmi, O wá àye lati gun "ori òke lọ on nikan, lati gbadura." Ọjọ wa gbogbo le kún fun iṣẹ ṣiṣe, o le rẹ̀ wá tán patapata, ṣugbọn ẹ jẹ ki a tẹle apẹẹrẹ Jesu ki a si wá akoko lati gbadura. Nigba pupọ ni ara aarẹ maa n lokun lẹyin akoko adura. Dajudaju ara Jesu mokun fun irin-ajo Rẹ̀ lori omi okun ti n rú, lẹyin ti O ti gbadura. Awa naa yoo le ni iranwọ si i lati le la igbi omi okun kọja lẹyin ti a ba ti gbadura.

Ni iṣọ kẹrin, tabi laaarin agogo mẹta si mẹfa owurọ, ni awọn ọmọ-ẹyin ri ti Jesu n rìn lori okun. Wọn kò tete mọ Ọn lakọkọ, ṣugbọn nigba ti wọn fi ibẹru kigbe, Jesu fi ọkàn wọn balẹ bayii pe, "Ẹ tújuka; Emi ni; ẹ má bẹ̀ru." Nigba pupọ ninu wahala tabi aisan, a ki i mọ̀ pe Olugbala wà nitosi; ṣugbọn bi a ba kigbe pe E ninu ipọnju wa, a oo gbọ́ ohùn Rẹ̀ pe, "Emi ni, ẹ má bẹ̀ru."

**Titẹjumọ Jesu**

Peteru fẹ́ rìn lori omi lọ sọdọ Jesu, oun si n rin lọ lori omi niwọn igba ti o tẹjumọ Jesu. Ṣugbọn nigba ti o wo riru okun, ẹru ba a, o si bẹrẹ si i rì. Niwọn igba ti a ba ti n tẹjumọ opin irin-ajo wa a o le la a já; ṣugbọn bi a ba ti bẹrẹ si wo gbogbo ohun wọnni ti o yí wa ká, a o daamu a o si ri sinu ainireti. Ọrọ ẹri Paulu ni pe, "Emi kò kà ara mi si ẹniti ọwọ́ rẹ̀ ti tẹ̀ ẹ na: ṣugbọn ohun kan yi li emi nṣe, emi ngbagbe awọn nkan ti o wà lẹhin, mo si nnọgà wò awọn nkan ti o wà niwaju, Emi nlepa lati de opin ire-ije nì fun ère ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:13, 14).

**Adura Peteru**

Nigba ti Peteru bẹrẹ si i ri, o kàn kigbe bayii pe, "Oluwa, gbà mi," lẹsẹkẹsẹ Jesu na ọwọ Rẹ̀ O si fà á. Adura kukuru ni eyi, ṣugbọn o jade lati ọkàn otitọ ẹni ti o n rì. Ọpọlọpọ eniyan ni o ti kigbe ninu idaamu pe, "Oluwa, gbà mi", wọn si ti mọ pe ọwọ́ naa jade wá lati gbà wọn.

**Igbagbọ**

“Iwọ onigbagbọ́ kekere, ẽṣe ti iwọ fi nṣiyemeji?” Igbagbọ́ yoo gbé ni leke omi; iyemeji yoo ri ni si isalẹ ibú. Paulu fun wa ni iroyin nla nipa ohun ti igbagbọ́ ṣe ni ori kọkanla Heberu. Iṣẹ iyanu n ṣe lonii nipa igbagbọ́ -- arun ti ko gboogun n sàn; a n dá awọn onde ẹ̀ṣẹ silẹ. Igbagbọ́ ayebaye a maa fun ni ni agbára ayebaye.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Jesu ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ fi lọ si aṣálẹ̀?
2. Iha wo ni Jesu kọ si ọpọ eniyan ti n bọ̀?
3. Ki ni O ṣe?
4. Ki ni awọn ọmọ-ẹyin fẹ ṣe nipa ati jẹun awọn ọpọ eniyan naa?
5. Awọn ta ni pín ounjẹ naa? bawo ni a ti ṣe eto awọn eniyan?
6. Ki ni Jesu ṣe ni alẹ́ ọjọ naa ki O to lọ bá awọn ọmọ-ẹyin?
7. Ki ni ọrọ ti Jesu sọ nigba ti awọn ọmọ-ẹyin fi ibẹru kigbe?
8. Ki ni igbe Peteru nigba ti o bẹrẹ si i rì?
9. Ki ni ohun ti awọn ero ọkọ wí nipa Jesu? ki ni si mu wọn sọ bẹẹ?
10. Darukọ oniruuru iṣẹ iyanu Jesu ninu ẹkọ yii.